AKIYESI

Ẹ sare tete wa ra awọn ọja ti o ya nile wọnyi:-
Cash and Rent Recipt 6s dozen, £2 15s gross, Calendar 1958, 4s 6d dozen, £2 8s gross, Gbedegbeyo Hausa £1 4s dozen, £12 8s gross, Goldsmith Receipt, complete set 17s 6d, ati orisirisi ọja be.
A nte iwe fun Sosi, Ile-Iwe Egbe ati bebe, ao te kiakia, yio si te yin lorun. Ẹ kowe si:- Manager

*Iyeru Press and Bookshop 68 Clifford Street, Ebute-Metta*

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

AKIYESI

E ma ka iwe Irohin Imọlẹ nigbagbogbo nitoripe itan aladun mẹta kan yio bẹrẹ ninu rẹ laipẹ yi. Ekini ni itan Kọgbọn ninu eyi, orire ọmọ nbẹ lọwọ iya rẹ (apakini) itan igbesi aiye awọn ayaba ati awọn ọlọgbọn aiye (apakeji) itan igbesi aiye awọn ọrẹ meji oni-,ibiti Eko ati Olọṣa Ilọrin (apakẹta)

VOL. I No. 30, WEDNESDAY 22, JANUARY — JANUARY, 28, 1958 KỌBỌ KAN

# Enia Dudu Ti Beresi De Ipo Giga Ni P & T

OLOYE S. L. Akintola ti o nse olotu tabi alase lori gbogbo oko ofurufu ati awon ohun ti o ngbe ni rin, tabi ti a nran nise (Aviation and P&T) lati ilu kan si ekeji lo so nigbangba mujumuwa wipe, nisisiyi nibi ise Post and Telegraph, ti beresi gbe awon enia dudu si ipo giga tabi ipo oyinbo, nitori **ki ibise na le di ti enia dudu.**

Awọn mejidilọgọta ninu awọn ọmọ ilẹ wa ni a nkọ lọwọ nisisiyi fun ipo giga awọn mẹtalelogun ni a ran lọ silu oyinbo lati kọ iṣẹ Elẹrọ (Engineer) ati paapa fun iṣẹ Tele-Communication, awọn mẹtadilogun wa nilu Gẹsi.

Awọn ipo ọga mejidilogun le lẹgbẹta to wa nilẹ nisisiyi, ti o jẹ pe awọn ajeji mọkandinlọgọfa lo nlo diẹ ninu awọn ipo ọga na ninu wọn ni a fi ipo mẹtadilọgọrun ṣe agbaṣe.

Ọlọla Oloye Akintọla sọ wipe, on sa gbogbo agbara on lati ri wipe iṣẹ Post Office di ibi iṣẹ enia dudu. Awọn ọmọ ẹgbẹ P & T sọ lati ẹnu akọwe wọn K. E. Ogbe wipe, ẹniti o tọ ni a nfi sidi nkan, on ripe Oloye S. L. Akintọla ni iṣẹ yi tọ si, on ni ẹniti yio ba wọn yi Palava & trouble padasi Peace & Tranquility.

# SHOYINKA TUN GBE DE

Turari fun Arisiki lati ilẹ India 10/6d
Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Ẹsin Ojiṣẹ nla Muhammad 7/6d
Kurani Esumẹta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu mẹrindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan ati Nofila Oru Oṣu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbẹyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun 5/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Turari Itaja 10/6d
Turari Ẹyọnu Ajẹ 10/6d
Abẹla Adura (Dragon Candle) fun Adura tete Dami lohun 15/-6d

Fi owo ransẹ si:-
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin.

# IJONGBON BE SILE NI OKITIPUPA

**Okitipupa**

Irohin kan wa wipe, rogbodiynn kan be silẹ nilu Okitipupa larapa sanwo ori, nko sanwo ori, ti o si dogun ohun ti ijoba ni lati ko awọn ọlọpa pẹlu ihamọra ogun lọ di awọn ara ilu na mọ.

Enia marundilọgọfa ni ọwọ Ijọba tẹ lara ọrọ owo ori yi, nigbati nwọn gbe ẹjọ na de iwaju adajọ, enia mẹrindi-lọgbọn lo jẹbi ọrọ na awọn meje pere lo ri owa san lati fi tan ọrọ wọn awọn yoku lọ si ẹwọn.

Ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun awọn mẹrindilọgbọn ti nwọn ba ṣe ẹjọ na ni pe, nwọn nṣe ikilọ fun awọn enia pe, nwọn ko gbọdọ sanwo ori.

A gbọ wipe, awọn ọlọpa si mbẹ lẹnu iwadi nipa ọrọ yi ni Irele, nitoripe ilu yi lo tobi ju ni ilẹ Okitipupa, ati pe ni gẹrẹ ti awọn ọlọpa de Irele, ni awọn alakatakiti na ti filu silẹ.

# Aso Wiwo Di Ijogbon ninu Ilewe

Ọmọde kekere kan ti o nka iwe kẹta nilewe lo wọ ẹwu bi awọn ọmọ Boma lọ silewe, eyiti o di ijọgbọn si ọmọ na lọrun tobẹ ti Olukọ-agba fi nilati le ọmọ na pada sile nigbati ariwo pọ.

Iru ẹwu ti ọmọ na wọ ti o di ijọgbọn na ni ẹwu singilẹti kan ti nwọn ya fansi ẹiyẹ ibaka si ni igba-aiya, yẹlo ni ẹwu na, nwọn si kọ orukọ yi si lara wipe, "Boma Boy"

Olukọ-agba sọ fun awọn obi ọmọ na wipe, on ko fẹ ki ọmọ na tun wọ iru aṣọ bayi wa silewe mọ. Olukọ na fiye awọn obi ọmọ na wipe, ọna ti nwọn ba fi ẹsẹ ọmọ wọn le, ni yio tẹ, on si mọ daju wipe ko si obi kan ti inu rẹ yio dun lati ri pe ọmọ on nhuwa gẹgẹbi ti awọn ọmọ Boma.

Inu bi awọn iya ọmọ na si ọrọ ti Olukọ-agba na sọ. Baba ọmọ na ti gbọ agbọye ohun ti Olukọ na wi. Ṣugbọn ọrọ ko ye iya ọmọ na rara, nṣe lo bu gbaragada, ti o tẹdimọlẹ ti o si nfọ wipe, Otutu lo mu ti on fi wọ Singilẹti ti o moru, ẹnikan ko si le kọ on ni iru aṣọ ti ọmọ on yio wọ. Ọmọ na na yio tun wọ ẹwu Boma lọ si ile iwe lọjọ keji, bi ẹnikan ba tun le ọmọ na, on yio gba Lọya ti oluwarẹ. ỌRỌ OLOTU:- Nitori iru iwa bayi ni nwọn ṣe da aṣọ Uniform silẹ ni ilewe.

E MA KA IROHIN IMOLE KI E SI MA POLOWO OJA YIN SIMU RE

# IMOLE

ESIN ORO WA: IMOLE DE OKUNKUN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*

**16, Bamgbose Street, Lagos.**
**Telephone: 21985**

*London Office—*
*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

FUN OWO "IROHIN IMOLE" ODUN KAN EKO—ŞILE MERIN KOBO MERIN (4/4d)
Ilu miran ni Naijria ati Oke-okun Şile mefa Kobo mefa 6/6d)


## OWO ERU HA TUN BERE NI BI ?

Ohun ti o mu awa oniwe yi şe ibere oke iwe ose yi nipe aşa gbigbe omo-olomo yi ko dawo duro rara, awon agba lo ma npowe pe Agba ki wa ni ilu kori omode pa. Tani agba na? Awon ni Ijoba, nitoripe Ijoba ko gbodo wa larin ilu ki ohun ti ko to si ma şele lai ko şe eto to to. Aito na bere lati odo Alabi ti o ti koko ji omo meta gbe lekan aseyinwa-aseyinbo nwon fi si ewon odun marun, eyi dabi eni wipe idajo ewon odun marun koto rara nitoripe enito jale to ngbe nkan ini lasan won nfii sewon odun gboro iyen ni wipe ohun ini ju omo lo ni tabi kini idi re? Nitori ti a ba fi ogbon si ohun ti a nşe ko si bi enia tile ni owo to ti Olorun ko ba fun l'omo, ko le fi owo re ra omo, odo Olorun ni omo ti nwa.

Ti a ba si wo daradara ona orişirişi ni nwon ngba fi gbe omo nisisiyi, ti ko ba si idi, "Obinrin ki je Kumolu" toto o şe bi owe. Eyi mu wa ranti ni aşale ojo kan ninu odun ti o şeşe koja yi ni idi Bossi Oyingbo ni a joko ti a nşe inaju ni a ri Ogbeni kan ti o wa ninu moto re duro bi eniti o duro de enia kan a şe o fe gbe enikeni ni, bi omobinrin kan si ti duro ti o nduro de bosi ni arakunrin yi si pe obinrin na wipe nibo ni o nlo ni omobinrin na si da lohun pe on nlo si Yaba, o si şi ilekun fun şugbon arabinrin na so fun u o ni o şe o ma lo fi oun gun oşe lati ri owo.

O si dabi eni wipe Alabi, Lawani Salisu ati awon bebe ti nwon ti ji omo gbe vi je iranşe fun awon ti o fe lo omo olomo fun ilosiwaju tiwon.

Nitori eyi a be Ijoba pe ti won ba le şe ofin miran ti yio fi je ki awon gbomogbomo yi le fi, fi iwa buburu yi sile yio si je didun inu gbogbo agbaiye nitoripe ohun ti a rope o şi nmu won hu iru iwa bayi ni pe Ijoba ko ni da ju ewon odun marun lo, nipa bayi iwa buburu yi tubo njoba si won lokan.

Ijoba e jowo e tubo ba wa tun ilu wa şe. Obi ko gbodo fi omo sile ninu ile re, obi ko gbodo ran omo re nişe nile keji pelu ijaya gbomogbomo ni yio ma ja won, eyi ku die ko to. Omo mi ku san ju omo mi sonu lo eyi dani loju pe Oluwa lo fun wa Oluwa lo si gba lo şugbon ewo ni jiji gbe? Enikeni ti o ba nşe eyi lati fi ko oro jo ko mo dajudaju wipe asan ni gbogbo oro re na yio je loju emi re.


DIRECT YOUR PRINTING JOBS TO:-

**MODUPE PRINTING PRESS**

16, Bamgbose Street,
Lagos.

Phone 21985


# Iwe Si Olotu

## IMORAN FUN MUSULUMI OMUPO

Olotu,

Mo fe ki e gbami laye lati fi ohun ti ondun mi lokan han awon Musulumi ti ilu Omupo. Ohun ti mo fe gba nwon ni iyanju fun on ni nipa esin Imale tiwa, A ko şe dogbandogba to nibi dida owo ni ona esin na. Ohun ti o mu mi so be sinu iwe ni wipe, ni igba meji ti a se idawo fun eko omo Mogaranta.

Idawo wa na ko lo to rara awon ti nwon ba fi je alaga li owo won ma nyato si ti awa toku, kini şe ti awon ti o niowo ninu awon Imale Omupo ki nna owo won si ona esin ti Olorun? Enikeni ti oba na owo re si ona esin ti Olorun, Olorun y o fi ilopo one mewa fun, kini şe ti awon ti o ba li owo ninu awon ti Imale ki nna bi awon onigbagbo ri Ilu wa ti nna wo nigba Ikore, ti Olorun tun nbun won ni owo si.

Enikeni to ba nna owo si ona ti Olorun ati ti Anabi ni Olorun yio tun ma fun li opolopo owo si, opolopo ninu awon oni Imale Ilu wa ni nwon ma lo nworan awon omo igbagbo nigbati nwon ba nşe Ikore, enikaluku li o ma ntaka bi Olorun ti şe fun ni owo si, ki nwon maşe jeki nwon bu awa na, kosi ninu awon onimale ti o li owo, ti o manso wipe ki nwon ki ogba owo ki nwon lo na si ona esin Olorun tabi ki o fi dupe ninu ohun ti Olorun şe fun.

Ati papa awon ti nwon je Mekunnu ninu awa Imale ti won ki işe olowo ki awon na ma gbiyanju ati owo si ona esin ti Olorun, ti enia kan ba na toro (3d) si Olorun yio fi pound pound ropo fun oluware, ati Imale ati igbagbo ilu Omupo, ki Olorun jeki aşe opolopo odun, Olorun yio fun onikaluku li owo.

J. Mojirola,
Omupo.

Inu mi yio dun bi, Olotu Irohin Imole bale te bami ie oro miyi jade ninu iwe re.

Ilu Omupe nfe ki awon Ijoba ile ariwa bawa risi Ilu wa na, awa nfe omi ero ati ina lentiriki pelu ki won ba wa foju si gbogbo kota ti won la ni arin oja wa kota na ko dara rara won ba gbogbo arin oja na je awa nfe k won bawa foju to gbogbo oro ti mo so yi ati pe ilu wa na kifi owori jafara rara owo ori ti njade ninu ilu wa na ni ododun oju egberun poun lo, (over £1000), ti awa nda lodun kan gbogbo awa ti awa ni idale na ni o da owo ori fun ogo ilu wa ni awa şe nda gbogbo owo na şugbon edun okan awa omo ilu Omupo ni mo ko sinu iwe yi ki Ijoba ile ariwa bawa gba gbogbo e dun okan wa yi wo ki won si fun wa ni dahun kia kia o.

Modupe lowo olotu Irohin Imole fun aye ti ogba mi yi, oko oba koni sa yin leşe amin ati aşe.

Emi ni:-
J. A. Fatunbi
Omo Omupo-via Offa

## ILU OGGA KABBA FE ATUNSE

Olotu,

Pelu ayo ni mo fi kiyin wipe eku ewu odun, ki Oluwa jeki afi alafia pari odun titun tia bosi yi amin.

Pelu iteriba ati owo ni mo fi tun ko iwe yi lati ran awon olotu Ijoba Ipinle Ariwa leti nipa iwe ebe mi fun ati şe GADA (bridge) eyi Omi, nitori ti mo ti nfi oju sona pe işe na bere ko si bere titi odun to koja fi pari (1957), mosi nero pe e o tete bawa moju to ati se GADA (bridge) na ninu odun tia bosi yi (1958) fun anfani Ijobi Idagba soke ile Yagba (Kabba Province).

Emi ni:-
Mathew Ade.,
Ogga (Kabba)

Olotu inu wa yio dun pupo, ti ebale bawa te ore kekere yi nipa ti oro Ilu Orra

Nipa oro oba ilu Orra ti won ndu ma rawon lowo, awa yio so nipa re ni agbara Olorun. Ki eyin onkawe Irohin Imole wayi ati awon omo Orra pataki egbiyanju lati marawe nani oseşe, nitori oro iluyin ti yio ma jade nibe.

Awa ni ti yin ni toto,
Memudu Yussuf Aremu,

